

# Community Discussion Guide for Malaria

PMI | U.S. PRESIDENT'S MALARIA INITIATIVE
LED BY USAID FROM THE AMERICAN PEOPLE | CDC

Breakthrough ACTION FOR SOCIAL & BEHAVIOR CHANGE

**Ibà: òkùnfà, àmì ìfura àti àmì àrùn**







# Ibà: òkùnfà, àmì ìfura àti àmì àrùn



## Ohun tí ó yẹ ko mọ̀

- Àìsàn ibà jẹ́ ohun tí ènìyàn ma ní tí ẹ̀fọn bá jẹ ènìyàn
- Tí a kò bá yára  e ìtọ́jú àìsàn ibà ó le di àìsàn tó lágbára to sì lè já sí ikú
- Àìsàn ibà á ma lágbára si ní ara àwon ọmọ tí kò tó ọdún márún ati àwon aláboyún
- A lè dènà aisan iba, a lè  e ìtọ́jú rẹ a sì lè wò ó sàn.
- **Orísi aisan iba méjì lówà**
- **Ibà tí kò lè púpọ̀**
- **Akọ ibà**
- Ibà tí kò lè púpọ̀ máa ń wá pẹ̀lú àwọn àmì aisan díẹ̀díẹ̀ bí ara gbígbóná, ẹ̀fọ́rí, enu kíkorò, ara rìro, àti bẹ̀ẹ̀ bẹ̀ẹ̀ lọ, tí ó má a ń kúrò lára pátápátá tá a bá tètè bójú tó
- Akọ ibà yàtọ̀ ó sì léwu púpọ̀, àwọn àmì akọ ibà ni ara tí ó ń gbóná gan-an, àìperí tàbí gìrì, ààrẹ̀ ní gbogbo ara, èébì rẹpẹtẹ, ìnira láti mí, àìlètọ̀ tàbí ìtọ̀ kékeré, kí ìtọ̀ ẹni máa dúdú, ojú  lè di aláwọ̀ òféèfé, ètè àti  àtẹ́lẹwọ́ tí ó funfun.
- Tí a kò bá tètè bójú tó Ibà tí kò lè púpọ̀  ó lè yọrí sí akọ ibà

## Ohun tí ó yẹ ko se

- Sùn sínu àpò ẹ̀fọn lálaalẹ́ yípo ọdún láti dènà ẹ̀fọn tí n fa ibà
- Yára gbé ẹni tó bá ní akọ ibà lọ sí ilé ìwòsàn láì fi àkókò sòfò.
- Kó gbogbo ohun tí omi le dáregún sínú rẹ kúrò ní àyíká rẹ.

## Gbé ìgbésẹ̀ yi

- Dáàbò bo ara rẹ lọ́wọ ẹ̀fọn nípa sísùn sínu àpò èfọn lálaalẹ́ yípo ọdún

Dídènà àìsàn ibà - lílo àpò ẹ̀fọn alálòpé léraléra



# Dídènà àìsàn ibà - lílo àpò ẹ̀fọn alálòpé léraléra



| | |
|---|---|
| **Ohun tí ó yẹ ko mọ̀** | • Ònà ti kò ná ni lówó jùlọ tó sì rọrùn jù láti dènà ibà ni sísùn sínu àpò èfọn lálaalẹ́ yípo ọdún<br>• Sísùn sínu àpò èfọn lálaalẹ́ á ma dáàbò bo ẹbí lọ́wọ aisan iba, á sì ma mú àdínkù bá owó fún ìtọ́jú aisan ibà<br>• Àwọn ẹ̀fọn tó nfa aisan iba á ma jẹ ènìyàn jùlọ ni ọwọ́ ìrọ̀lẹ́ títí di àárọ̀ ojo keji.<br>• Tí o kò bá kó gbogbo ọwọ́ àpò ẹ̀fọn rẹ sí abẹ́ ibi ìbùsùn rẹ (yálà bẹ́ẹ̀dì tàbí ẹní) ẹ̀fọn le wọlé láti jẹ ó.<br>• Tí o kò bá rán àpò ẹ̀fọn rẹ nígbà tó bá ya ẹ̀fọn le wọlé láti jẹ ó<br>• Ní àfikún sí àpò ẹ̀fọn ọ̀fẹ́ tí ìjọba n pín, a lè rí àpò ẹ̀fọn rà ní ọjà àti ilé ìta òògùn.<br>• Tí o bá fún àpò ẹ̀fọn rẹ ní ìtójú tó péye, yòó  e lò pẹ́ si. |
| **Ohun tí ó yẹ ko se** | • Ra àpò ẹ̀fọn ní ilé ìta òògùn tàbí ọjà tí o kò bá ní àpò ẹ̀fọn ọ̀fẹ́ tí ìjọba pín.<br>• Sa sí abẹ́ ibòji fún wákàtí mẹ́rinlélógún kí o tó taá sí ibi ibùsùn rẹ.<br>• Sùn sínu àpò ẹ̀fọn rẹ lálaalẹ́ títí di òwúrọ̀<br>• Káa àpò ẹ̀fọn rẹ sókè araaro nítorí ìdọ̀tí, iná, àwọn ọmọdé tàbí eranko.<br>• Ráan tí ó bá fà ya. Gbìyànjú láti lo àpò ẹ̀fọn rẹ fún ìgbà pípẹ́ kí o tó ní tuntun.<br>• Rọra fọ̀ọ́ pẹ̀lu ọ ẹ tí kò ní sódà nínú, nígbà tó bá dọ̀tí NÌKAN kí o sì sáa sí abẹ́ ibòji láti gbẹ<br>• Ri wípé o kó gbogbo ọwọ́ àpò ẹ̀fọn rẹ sí abẹ́ ibi ìbùsùn rẹ dáada kí ẹ̀fọn má baà le wọlé sínú àpò ẹ̀fọn rẹ. |
| **Gbé ìgbésẹ̀ yi** | • Sùn sínu àpò èfọn lálaalẹ́ yípo ọdún láti dènà ẹ̀fọn tó nfa àìsàn ibà. |

**Wíwá ìtọ́jú ìyárakánkán fún ibà**






# Wíwá ìtọ́jú ìyárakánkán fún ibà






| | |
|---|---|
| **Ohun tí ó yẹ ko mọ̀** | • Ara gbígbóná jẹ́ àpẹẹrẹ wípé nkankan  ẹlẹ̀ nínú àgọ́ ara. Nítorínà ó  e pàtàkì láti lọ sí ilé ìwòsàn lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ tí ara rẹ bá ngbóná.<br>• Tí o bá lọ sí ilé ìwòsàn lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, wọn á lè mọ ohun tó fa ara gbígbóná, wọn á sì lè  e ìtọ́jú tó péye.<br>• Kì í  e gbogbo ara gbígbóná ni àìsàn ibà. Àwọn àìsàn míràn bíi catarrh, ibà jẹ̀funjẹ̀fun àti onírúurú àkóràn ló ma nfa ara gbígbóná.<br>• Ònà kan tó dájú láti mọ̀ tí ènìyàn bá ní àìsàn ibà ni láti  e àyẹ̀wò fún ibà<br>• Àyẹ̀wò ibà yi múnádóko èsì rẹ si dájú |
| **Ohun tí ó yẹ ko se** | • Gbogbo eni tó bá ní ara gbígbóná gbọ́dọ̀ lọ sí ilé ìwòsàn lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀<br>• Ò ì ẹ́ ètò ìlera yóò  e àyẹ̀wò fún ibà, ní sùúrù láti rí èsì àyẹ̀wò rẹ, kò ní gba àkókò.<br>• Tí àyẹ̀wò bá fi hàn pé o ní àìsàn ibà nìkan ni ò ì ẹ́ ètò ìlera yóò  e ìtọ́jú ibà fún ọ.<br>• Tí àyẹ̀wò bá fi hàn pé o kò ní àìsàn ibà ò ì ẹ́ ètò ìlera yóò  e ìwádi síwájú láti mọ ohun tó fa ara gbígbóná rẹ. |
| **Gbé ìgbésẹ̀ yi** | • Lọ sí ilé ìwòsàn lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ tí ara rẹ bá ngbóná. |

Ìtọ́jú tó múná dóko fún ibà



# Ìtọ́jú tó múná dóko fún ibà



## Ohun tí ó yẹ ko mọ̀

- Tí o bá bẹ̀rẹ̀ ìtọ́jú lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ tí èsì àyẹ̀wò bá fi hàn pé o ní àìsàn ibà, yoo dènà kí àìsàn ibà na di ohun tó le.
- ACT nìkan ni òògùn tí ó le  e ìtọ́jú àìsàn ibà dáradára.
- Kí òògùn yí le  i ẹ́ dáada, ó  e pàtàkì láti lo gbogbo ACT rẹ tán, bí ó tilẹ̀ jọ wípé ara rẹ ti yá.
- Bí ọmọdé bá bi òògùn yí láàrin ọgbọ̀n ì ẹ́jú tí ó lòó, ó ní láti tun lò.

## Ohun tí ó yẹ ko se

- Bẹ̀ẹ̀rẹ̀ ìtọ́jú àìsàn ibà lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ tí èsì àyẹ̀wò bá fi hàn pé o ní àìsàn ibà
- Lo òògùn ACT nìkan láti  e ìtọ́jú àìsàn ibà tí èsì àyẹ̀wò bá fi hàn pé o ní àìsàn ibà
- O ní láti lo gbogbo òògùn fún ìtọ́jú àìsàn ibà rẹ tán, bí ó tilẹ̀ jọ wípé ara rẹ ti yá.
- Má e  ẹ́ nkankan kù nínu òògùn ACT rẹ fún ọjọ́ míràn bí ó tilẹ̀ jọ wípé ara rẹ ti n yá
- Bí ọmọdé bá bi òògùn yí láàrin ọgbọ̀n ì ẹ́jú tí ó lòó, ó ní láti tun lò, kí o sì lọ sí ilé ìwòsàn láti gba òògùn ACT si.

## Gbé ìgbésẹ̀ yi

- Tí èsì àyẹ̀wò bá fi hàn pé o ní àìsàn ibà, Lo òògùn ACT nìkan kí o sì lòó parí

**Dídènà àìsàn ibà fún olóyún**







# Dídènà àìsàn ibà fún olóyún



| | |
|---|---|
| **Ohun tí ó yẹ ko mọ̀** | • Lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ tí obìrin bá mọ̀ pé òhun ti lóyún, lílọ fún ìtọ́jú olóyún (ANC) yóò fún ò ì ẹ́ ètò ìlera ní ànfàní láti mójútó ìdàgbà sókè ọmọ àti ìlera ìyá.<br>• Àìsàn ibà léwu púpò fún olóyún àti ọmọ inú rẹ<br>• Lílo òògùn SP yóò dènà àìsàn ibà nínú oyún<br>• Ohun tí ó dára ni kí ọkọ  e àtìlẹyìn fún ìyàwo rẹ kí ó sì tẹ̀le lọ fún ìtọ́jú aláboyún ANC |
| **Ohun tí ó yẹ ko se** | • Gbogbo olóyún ní láti bẹ̀ẹ̀rẹ̀ si ní lọ fún ìtọ́jú olóyún  (ANC) lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ tí ó bá mọ̀ pé òhun ti lóyún kí ó sì má a lọ títí yóò fi bímọ.<br>• Gbogbo olóyún GBỌ́DỌ̀ lo òògùn SP ní ìgbà ìtọ́jú aláboyún (ANC) ní iwájú ò ì ẹ́ ètò ìlera láti dènà àìsàn ibà<br>• Olóyún GBỌ́DỌ̀ máa sùn sínú àpò ẹ̀fọn lálaalẹ́ yípo ọdún<br>• Ó yẹ kí àwọn ọkọ má a  e àtìlẹyìn fún àwọn  ìyàwo wọn kí wọ́n sì gbà wọ́n níyànjú láti má a lọ fún ìtọ́jú aláboyún (ANC) déédé |
| **Gbé ìgbésẹ̀ yi** | • Bẹ̀ẹ̀rẹ̀ ìtọ́jú aláboyún (ANC) lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ tí ó bá mọ̀ pé o ti lóyún, má a lọ déédé, lo òògùn SP, kí o sì má a sùn sínú àpò ẹ̀fọn lálaalẹ́ yípo ọdún |

# Community Discussion Guide for Malaria

FOR A
MALARIA-FREE
NIGERIA

Play Your Part

PMI | U.S. PRESIDENT'S MALARIA INITIATIVE
LED BY USAID FROM THE AMERICAN PEOPLE CDC

Breakthrough ACTION
FOR SOCIAL & BEHAVIOR CHANGE